**Nípasẹ Ààrẹ**
**Dieter F. Uchtdorf**
Olùdámọ̀ràn Kejì Nínú
Àjọ Olùdarí Gbogbogbòò



# Ìdákọ̀ró tí a Fi Lélẹ̀ Ní Dídúró Gbọingbọin

Ní àìpẹ́ púpọ̀ sẹ́hìn mo ní ànfãní lati wà nínu ọkọ̀ ojú omi nlá kan ní bèbè odò ti Alaskà tí ó yanilẹ́nu Nigbati atukọ̀ náà ṣe ìpalẹ̀mọ́ fun ọkọ̀ náà lati duro ni òru ní ibi ìdára dúró tí ó jẹ́ inu igbo, ó fi ara balẹ̀ ṣe àyẹ̀wò ibẹ̀ ati awọn àyíká, gẹgẹbíi àyọrísí ti awọn rírú omi, jíjìn awọn omi náà, ati jíjìnnà rẹ̀ sí awọn ìdènà tí ó léwu. Nigbati ó tẹ́ẹ lọ́rùn, ó sọ ìdákọ̀ró kalẹ̀ kí ọkọ̀ náà le wà ní àìléwu kí ìdákọ̀ró rẹ̀ sì duro gbọingbọin, tí ó fún awọn èrò ni ànfãní lati yanu sí awọn ẹwà àgbàyanu ti awọn ohun tí Ọlọ́run dá.

Bí mo ti ń wo ãlà eti bèbè, mo bẹ̀rẹ̀ sí ríi pé ọkọ̀ náà ń sún ní ìwọ̀n tí ó fẹ́rẹ̀ má ṣeé fura sí pẹ̀lú iye kékeré atẹ́gùn ati agbara tí ó rọ̀ mọ́ọ̀. Bí ó tilẹ̀ rí bẹ́ẹ̀, ọkọ̀ náà dúró gbọnin ati ní àìkãrẹ̀ láàrin àkámọ́ tí òdiwọ̀n rẹ̀ jẹ́ nípa gígún okùn ìdákọ̀ró náà ati agbára ti ìdákọ̀ró náà.

Atukọ̀ náà kò gbé ìdákọ̀ró náà pamọ́ sínú ọkọ̀, ní àrọ́wọ́tó lati sọ̀ọ̀ kalẹ̀ nigbati ìjì líle bá dojúkọ̀ọ̀ nìkan. Rárá, ó ti so ìdákọ̀ró ọkọ̀ náà gẹ́gẹ́bíi òsùnwọ̀n adènà ó sì dá ãbò bo ọkọ̀ náà lọ́wọ́ ṣíṣí lọ sínú awọn omi tí wọn léwu tabi sísún díẹ̀díẹ̀ lọ sí àhámọ́ nigbati awọn èrò ati awọn òṣìṣẹ́ inú ọkọ̀ bá ní ìmọ̀lára ãbò.

Bí mo ṣe ń rò nipa ìran yĩ, ó hàn sí mi pé bi èyí kĩ ba ṣe ànfãní fun òwe kan, emi kò tĩ wa ọkọ̀ òfurufú rí.

## Ìdí Tí A fi Nílò awọn Ìdákọ̀ró

Èrèdí ti ìdákọ̀ró kan ni lati pa ọkọ̀ ojú omi mọ́ ni àìléwu ati ní ìdáàbòbò ni ibi ti a fẹ́ tabi lati ṣe ìrànwọ́ darí ọkọ̀ ní akókò ojú ọjọ́ búburú. Ṣùgbọ́n, lati le ṣe awọn èrèdí pàtàkì wọ̀nyí, níní ìdákọ̀ró kan lásán kò tó. Ìdákọ̀ró nã gbọdọ̀ gbórín, ṣeé gbẹ́kẹ̀lé, kí a sì lòó dáradára ni àkókò ati ní ibi tí ó yẹ.

Awọn ẹni kọ̃kan ati awọn ìdílé nílò awọn ìdákọ̀ró bákannáà.

Ìpèníja le wa gẹ́gẹ́bĩ ìjì nlá lati gbá wa kúrò ní ojú ọ̀nà kí ó sì halẹ̀ mọ́ wa lati gbé wa kọlu awọn àpáta. Ṣugbọn nígbàmírán bákannáà a máa ń wà ninu ewu nigbati ohun gbogbo bá dàbí ẹnipé ó wà ní abẹ́ ãbò—awọn afẹ́fẹ́ jẹ́jẹ́ ati awọn omi rọ́rọ́. Ni tootọ́, a le wà ninu ewu nla jùlọ nigbati a bá n sún ati tí ṣíṣípòpadà kéré débi pé a fẹ́rẹ̀ le má ríi.

## Ìhìnrere Ni Ìdákọ̀ró Wa

Awọn ìdákọ̀ró gbọdọ̀ gbórín, ní agbára, kí a sì ṣe ìtọ́jú rẹ̀ dáradára kí ó le wà ní igbaradì nigbati a bá nílò rẹ̀. Ní àfikún, wọn gbọdọ̀ jẹ́ síso mọ́ ìpìlẹ̀ kan tí ó tó lati gbé ìwọ̀n awọn agbara àdojúkọ.

Dájúdájú, ìhìnrere Jesu Kristì ni irú ìdákọ̀ró náà. Ó jẹ́ pípèsè lati ọwọ́ Ẹlẹ́dàá ti àgbáyé fun èrèdí àtọ̀runwá kan ati ṣíṣe lati ṣètò ãbò ati ìtọ́ni sí awọn ọmọ Rẹ̀.

Kíni ìhìnrere, lẹ́hìn ohun gbogbo, bíkòṣe èrò Ọlọrun lati ra awọn ọmọ Rẹ̀ pádà ati lati mú wọn pada sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀?

Lẹ́hin mímọ̀ pé ó jẹ́ ìṣẹ̀dá gbogbo nkan lati sún, a gbọ́dọ̀ fi awọn ìdákọ̀ró wa lélẹ̀ lori ìpìlẹ̀ òtítọ̀ ti ìhìnrere. Wọn kò gbọdọ̀ jẹ́ rírọ̀ sílẹ̀ ṣã sí orí awọn yanrìn ìgbéraga tàbí kí ó mã tiraka kan ibi iwájú awọn ìdánilójú wa.

Ní oṣù yi a ni anfãní kan lati gbọ́rọ̀ lati ọ̀dọ̀ awọn ìránṣẹ́ Ọlọ́run ninu ìpàdé àpapọ̀ gbogbogbòò ti Ijọ. Awọn ọ̀rọ̀ wọn, ní àsopọ̀ pẹ̀lú awọn ìwé mímọ́ ati awọn ìmísí ti Ẹ̀mí, npèsè ìpìlẹ̀ àgbékalẹ̀ tí ó ní ãbò tí ó si dúró ti awọn iyì ati awọn ìlànà ayérayé èyítí a le so awọn ìdákọ̀ró wa mọ́ kí a ba lè wà ní ìdúróṣinṣin ati ninu ãbò lãrin awọn ìlàkàkà ati awọn àdánwò ayé.

Wòlĩ ìgbãnì Hẹ́lámánì kọ́ni, "Lori àpáta Olùràpadà wa, ẹnití íṣe Krístì, Ọmọ Ọlọ́run, ni ẹyin nilati kọ́ ìpìlẹ̀ yin lé, pé nigbati èṣù bá sì fẹ́ ẹ̀fũfù líle rẹ̀ wá, bẹ̃ni, ọ̀pá rẹ̀ ninu ìjì, bẹ̃ni, nigbati gbogbo awọn òkúta yìnyín rẹ̀ ati ìjì líle rẹ̀ bá rọ̀ lé yín kò le ní agbára lorí yín lati fà yín sínú ọ̀gbun òṣì ati ègbé àìlópin, nitori àpáta èyítí a kọ́ yín lé lórí, èyítí ènìyàn kò lè ṣubú lórí rẹ̀ bí wọ́n bá kọ́ lé e lórí" (Helaman 5:12).

### Iyì Awọn Ìdákọ̀ró Tí A Fi Lélẹ̀ Gbọingbọin

Ìgbé ayé ní ọ̀nà kan lati fi yẹ awọn ìdákọ̀ró wa wò ati dídán wa wò lati sún. Bí ó tilẹ̀ rí bẹ̃, bí a bá gbé awọn ìdákọ̀ró wa lélẹ̀ dáradára nínu àpáta Olùràpadá wa, wọn yío dúró—bí ó ti wù kí ìjì nã ní agbára tó, kí rírú omi nã le tó, tabi kí ríru sókè omi nã ga tó.

Dájúdájú, a kò ṣe ọkọ̀ ojú omi lati duró láìyẹsẹ̀ ní bèbè kan ṣùgbọn lati gbé ìdákọ̀ró sókè kí ó sì rìn ninu awọn òkun ayé. Ṣugbọn èyĩnì jẹ òwe fun àkókò míràn.

Fún ìsisìnyí, mo ní ìtura ninu mímọ̀ pé ìdákọ̀ró ti ìhìnrere ati àpáta ti Olùgbàlà wa yí ó pa wá mọ́ ní dídúró ati ní àìléwu.

Irú ìdákọ̀ró bẹ̃ yío pa wá mọ́ kúrò ninu sísún sí ínú ewu ati ìjàmbá. Yíó fun wa ni ànfãní ológo lati gbádùn awọn ẹwà ti kò ní àfiwé ti ìgbé ayé tí ó ńyípadà ṣã ti ó sì kún fun ìmísí.

Ìgbé ayé rẹwà ó sì yẹ ní gbígbé. Ìjì líle, ẹ̀fũfù, ati awọn ìṣẹ̀lẹ̀ lọ́wọ̀lọ́wọ̀ le dan wa wo lati sún sí inú awọn ewu rírí ati àìrí, ṣugbọn iṣẹ́ ìhìnrere ati agbára àtọ̀runwá Rẹ̀ yío pa wá mọ́ sí ojú ọ̀nà wa padà sí bèbè àìléwu ti Baba wa Ọrun.

Nígbànã, ẹ máṣe jẹ́kí a gbọ́ *awọn ọ̀rọ̀* ìpàdé àpapọ̀ gbogbogbòò ti Osù Kẹrin lásán ṣugbọn bakannã *kí a ṣe àmúlò* awọn ọ̀rọ̀ wọn gẹ́gẹ́bĩ ìdákọ̀ró tí a fi lélẹ̀ gbọingbọin sí ìgbé ayé wa ojõjúmọ́.

Kí Ọlọ́run bùkún kí Ó sì tọ́ wa ninu akitiyan tí ó tóbi tí ó sì ṣe pàtàkì yĩ!

---

### ÌDÁNILẸ́KỌ́ LÁTI INU IṢẸ́ YÌÍ

Rò nípa sísọ̀rọ̀ lori ṣíṣe pàtàkì awọn ìdákọ̀ró tí ó hàn nínú bí ìdílé Léhì ṣe wọ ọkọ̀ oju omi lọ sí ilẹ̀ ìlérí (wo 1 Nephi 18). O lè tọ́ka sí 1 Nephi 18:11–15, àkókò kan tí a dè Nephi, Liahona kọ̀ lati ṣiṣẹ́, ọkọ̀ nã sì di wíwà lati ọwọ awọn ìjì líle búburú. Kíni awọn àyọrísí tí a mã ń kojú nigbati a kò bá ní ìdàkọ̀ró àìléwu ninu ìhìnrere? Bákannã o lè tọ́ka sí 1 Nephi 18:21–22 ki o si sọ̀rọ̀ lórí bí a ṣe le rí ãbò nípa yíyí padà sí Olùgbàlà.

## ỌDỌ́

# Ìpàdé Gbogbogbòò ati Èmi

**Láti Ọwọ́ Sarah Deeks**

Mo ti mã ń rò pé ìparí ọ̀sẹ̀ ti ìpàdé àpapọ̀ gbogbogbòò mã n gùnjù ó sì mã ń sú ni, ṣùgbọ́n bí àsìkò ti ṣe kọjá, mo ti wá nífẹ̃ rẹ̀ mo sì mã ń fi ojú sọ́nà sí i. Ìparí ọ̀sẹ̀ ti ìpàdé àpapọ̀ gbogbogbòò le jẹ́ títún agbára ẹni ṣe nínú ẹ̀mí, ṣùgbọ́n ó rọrùn lati jẹ́kí awọn ìmọ̀lára wọ̀nyi ṣa nigbati ìgbé ayé àtẹ̀hìnwá bá tẹ̀ síwájú ní Ọjọ́ Ajé. Díẹ̀ nínu awọn èrò inú wọ̀nyí ti ràn mí lọ́wọ́ lati tẹ̀síwájú ní ṣíṣe àmújáde ohun púpọ̀ lati inú ìpàdé àpapọ̀ bí ó ti lè ṣẹ̀ṣe.

Mo mã ń gbaradì fún ìpàdé àpapọ̀ nípa kíkọ awọn ìbẽrè sílẹ̀, ati lẹ́hìnnã mo mã nṣe àkọsílẹ̀ bí ìdáhùn ṣe nwá sí awọn ìbẽrè mi. Ní ìgbẹ̀hìn, mo fẹ́ràn lati sọ awọn ọ̀rọ̀ ìpàdé ati orin kalẹ̀ lati LDS.org kí n sì fi wọn sí orí ohun èlò MP3 kí n le ba fi etí sí awọn ọ̀rọ̀ tàbí orin bí mo ṣe n bá iṣẹ õjọ́ mi lọ. Bákannã mo nífẹ̃ lati ṣe àṣàrò ninu Liahona *ti ìpàdé àpapọ̀.* Mo mã ń fãlà sí ati kọ àkọsílẹ̀ sí inú ẹ̀gbẹ̃gbẹ́ èyí tí ó jẹ́ tèmi. Ní ìgbà tí àkókò ìpàdé àpapọ̀ míràn yí ó fi yí wá, mo ti lo magasínnì mi dáradára. Nígbàmíràn ẹbí mi mã ń ṣe àṣàrò lórí awọn iṣẹ́ rírán lápapọ̀ nínu ìpàdé ìrọ̀lẹ́ ẹbí.

Ṣíṣe ìpamọ́ ìmísí tí a ní ìmọ̀lára rẹ̀ nínú ìpàdé àpapọ̀ pẹ̀lú wa ati títẹ̀síwájú lati mã kọ́ ẹ̀kọ́ ninu awọn iṣẹ́ nã gba iṣẹ́ ṣíṣe, ṣùgbọ́n ṣíṣe èyí ti jẹ́ ìbùkún nlá fún mi. Mo ti gba okun ati ìtọ́ni púpọ̀ ni awọn àkókò àìní nípa ṣiṣe àṣàrò nínu awọn iṣọ́ rírán lati inú ìpàdé àpapọ̀ gbogbogbòò, mo sì mọ̀ pé awọn iṣẹ́ wọ̀nyí jẹ́ nípa ìmísí.

*Olùkọ̀wé n gbé ní Toronro, Canada*

## ÀWỌN ỌMỌDÉ

### Fi Ìdákọ̀ró Rẹ Lélẹ̀

Kíni yíó pa yín mọ́ ní síso mọ́ ìdákọ̀ró sí ìhìnrere? O lè fẹ́ ya àwòrán ọ̀kọ̀ ojú omi kan ati ìdákọ̀ró kan. Lẹ́hìnnã o le fi gúlũ tàbí tẽpù lẹ̀ sí ẹ̀gbẹ́ ìdákọ̀ró rẹ èyíkéyĩ awọn àwòrán awọn ènìyàn tàbi awọn ohun tí yio ràn ọ̀kọ̀ ojú omi rẹ lọ́wọ́ lati dúró láìléwu. Rántí, Olùdarí Uchtdorf sọ pé Jésù Krístì, awọn wòlĩ òde òní, ati awọn ìwé mímọ́ jẹ́ awọn ìdákọ̀ró tí ó dára jùlọ fún ìgbé ayé wa.

© 2014 lati ọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹ̀ẹ́ ní USA.
Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/13. Àṣẹ Àyípadà èdè: 6/13. Ìtumọ̀ ti *First Presidency Message, April 2014*. Yoruba. 10864 779

# Iṣẹ́ Ìránṣẹ́ Àtọ̀runwá ti Jésù Krístì: Olùgbàlà ati Olùràpadà

*Fi tàdúrà tàdúrà ka ohun èlò yĩ kí o sì wákiri lati mọ ohun ti õ ṣe àbápín. Báwo ni níní òye ìgbé ayé ati iṣẹ́ ìránṣẹ́ Olùgbàlà ṣe fikún ìgbàgbọ́ yin ninu Rẹ̀ ati bùkún awọn tí ẹ nṣe olùṣọ́ lé lórí nipasẹ̀ Abẹniwò kíkọ́ni? Fún ìmọ̀ sĩi, lọ sí **reliefsociety.lds.org**.*

**Ìgbàgbọ́, Ìdílé, Ìrànlọ́wọ́**

*Èyí ni apákan nínú oníruurú àwọn ọ̀rọ̀ Abẹniwò Kíkọ́ni tí ó ńfi awọn abala ti iṣẹ́ ìrànṣẹ Jésù Olùgbàlà hàn.*

Lãrin awọn orúkọ alápèjúwe pàtàkì jùlọ ti Jésù Krístì ni Olùràpadà," ni Alàgbà D. Todd Christofferson ti Ìgbìmọ̀ awọn Àpóstélì Méjìlá sọ. "*Ràpadà* túmọ̀ sí lati san ojúṣe kan tàbí gbèsè kan. *Ràpadà* bákannã tún le túmọ̀ sí lati gbàlà tàbí dá sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bĩ nipa sísan iye owó kan. . . . Olukúlùkù awọn ìtumọ̀ wọ̀nyí dábã orísìrísì awọn ẹ̀yà Ìràpadà nlá ti Jésù Krístì ṣe yọrí nípasẹ̀ ètùtù Ẹ̀ṣẹ̀ Rẹ̀, èyí tí, ìwé ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ (dikiṣánnárì) ṣe àpèjúwe rẹ̀ bĩ, 'lati kó yọ nínú ẹ̀ṣẹ̀ ati awọn ìjìyà rẹ̀, gẹ́gẹ́bĩ nípa ètùtù ṣíṣe fún ẹlẹ́ṣẹ̀ nã.'"[1]

Linda K. Burton, olùdarí gbogbogbòò Ẹgbẹ́ Arannilọ́wọ́, sọ pé: "Baba Ọ̀run . . . rán Ọmọ Bíbí Rẹ̀ Kanṣoṣo tí ó pé lati jìyà fun awọn ẹ̀ṣẹ̀ wa, awọn ìrora ọ̀kàn wa, ati gbogbo ohun tí ó dàbí ẹnipé kò dara tó ninú ìgbé ayé ẹnìkõkan wa.

". . . Obìnrin kan ẹnití ó ti la ọ̀pọ̀ ọdún àdánwò ati ìṣòro kọjá sọ pẹ̀lú omi ojú rẹ̀ pé, 'Mo ti wá ní òye pé èmi dàbí ogún-dọ́là gbígbó kan—rírun, yíya, dídọ̀tí, ní ìlòkulò, ati tí ẹ̀rù nbà. Ṣùgbọ́n . . . Mo ṣì pé iye ogún-dọ́là ní kíkún.' Obìnrin yĩ mọ̀ pé òun . . . ṣì péye tó sí [Ọlọ́run] lati rán Ọmọ Rẹ̀ lati ṣe ètùtù fún un, bĩ ẹnìkan. Olukúlùkù arábìnrin ninu Ìjọ nílati mọ ohun tí obìnrin yĩ mọ̀."[2]

## *Láti Àwọn ìwé Mímọ́*

2 Nephi 2:6; Helaman 5:11–12; Moses 1:39

## *Láti Inú Ìtàn Wa*

Májẹ̀mú Titun ní awọn àkọsílẹ̀ ti awọn obìnrin ẹnití wọn lo ìgbàgbọ́ wọn nínú Jésù Krístì, tí wọn kọ́ ti wọn sì gbé ìgbé ayé awọn ìkọ́ni Rẹ̀, ti wọn sì jẹ́rĩ sí iṣẹ́ ìránṣẹ, awọn iṣẹ́ ìyanu, ati ọlá nlá Rẹ̀.

Jésù sọ fun obìnrin nã ní ibi kànga:

"Ẹnikẹ́ni tí ó bá mu nínu omi tí emi ó fifún un, òrùngbẹ kì yío gbẹ ẹ́ mọ́ láé; ṣùgbọn omi tí emi ó fifún un yío di kànga omi ninu rẹ̀, ti yío ma sun sí ìyè àìnípẹ̀kun.

"Obìnrin nã sì wí fun un pé, Ọgbẹni, fún mi ni omi yi, ki òrùngbẹ kí ó máṣe gbẹ mí . . . .

"Mo mọ̀ pé Messia mbọ̀ wá, . . .: nigbati òun bá dé, yío sọ ohun gbogbo fun wa.

"Jesu wi fun un pé, Emi ẹniti mba ọ sọ̀rọ̀ yi ni òun.

Oun "si fi ládugbó rẹ̀ sílẹ̀" ó sì jẹ́ ẹ̀rí Rẹ̀ ninu ìlú. (Wo John 4:6–30.)

**ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁNPẸ̀**

1. D. Todd Christofferson, "Redemption," *Ensign* or *Liahona,* May 2013, 109.
2. Linda K. Burton, "Njẹ́ Ìgbàgbọ́ ninu Ètùtù ti Jésù Krístì jẹ́ Kíkọ ninu Awọn Ọkàn Wa?" *Ensign* or *Liahona,* Nov. 2012, 114.

### *Kíni Mo Lè Se?*

**1.** Báwo ni a ṣe le fi imõre hàn si Olùgbàlà ati Olùràpadà, Jésù Krístì?

**2.** Báwo ni a ṣe lè pín nínú awọn ìbùkún ètùtù ẹ̀ṣẹ̀ ti Olùgbàlà wa nínu ìgbé ayé wa?

© 2014 lati ọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹ̀ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/13. Àṣẹ Àyípadà èdè: 6/13. Ìtumọ̀ ti *Visiting Teaching Message, April 2014*. Yoruba. 10864 779